# Ilu lilu nibi inawo tabi ajoyọ ko ba Ẹsin Islam mu

[ Yorùbá -Yoruba - يوربا ]

Oju Ewe Ayelujara

IBEERE ATI IDAHUN NIPA ỌRỌ ẸSIN ISLAM

Labẹ Amojuto:

Sheikh Muhammad Sọọlih Al-munajjid

Itumọ si ede Yoruba: Rafiu Adisa Bello

Atunyẹwo : Hamid Yusuf

2015 - 1436

IslamHouse.com

# الطبول في المناسبات منكر

« بلغة اليوربا »


موقع الإسلام سؤال وجواب

الشيخ محمد صالح المنجد

ترجمة: رفيع أديسا بلو

مراجعة: حامد يوسف



2015 - 1436

IslamHouse.com

# IBEERE ATI IDAHUN LORI ỌRỌ ẸSIN ISLAM

## FATWA: [12929]

**IBEERE:**

**Kinni idajọ lilọ si ibi apejẹ tabi ajọyọ, ti awọn nkan ti ko ba ẹsin Islam mu gẹgẹ bii lilu ilu wa nibẹ, ti o si jẹ wipe ẹniti o pepe si apejẹ naa jẹ ọkan ninu awọn alasunmọ ẹni, ti awọn nkan ti ko ba ẹsin mu yi si wa nibẹ?**

.................................................................

**IDAHUN:**

Ọpẹ ni fun Ọlọhun.

Ko lẹtọ lati jẹ ipe fun iru ajọyọ bayi pẹlu awọn nkan ti o lodi si ẹsin Islam ti o wa nibẹ. Bakannaa, ti wọn ba n mu ọti tabi siga nibẹ, tabi wọn n wo fiimu ti sise afihan ihooho ara wa nibẹ, tabi awọn ọkunrin ati obinrin ti wọn kii se ẹlẹtọ ara wọn n wa papọ nibẹ, tabi awọn obinrin n fi ẹwa ara wọn han sita nibẹ.

Sugbọn ti o ba jẹ wipe lilọ sibẹ rẹ le jẹ okunfa ayipada awọn nkan naa tabi ki o dinku, tabi o jẹ wipe ti o ba lọ si ibẹ, awọn ti wọn n se awọn aburu naa yoo se apọnle rẹ, ti wọn yoo si fi awọn nkan naa silẹ, nigba naa o le lọ sibẹ. Sugbọn ti o ba jẹ wipe lilọ sibẹ rẹ ko le mu ayipada ba awọn iwa abuku naa, ko lẹtọ fun ọ lati lọ rara, koda ki o jẹ alasunmọ rẹ ni ẹni ti o pepe si apejẹ naa.